The Chief Secretary to the Government.

Ọrọ Ẹjọ Eleko Pataki mbẹ ninu Eko Akete yi ni kikun.

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. NO. 276 SATURDAY, MAY 26, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

**White's Radical Gonkiller.**

:o:

(NATIVE.)

*[ A complete cure for old and fresh Gonorrhoea. ]*

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

NIGERIAN SECRETARIAT 1. 6. 28 LAGOS

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

*[ Fun Atọsi lailai ati titun ]*

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa origi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si i jẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.

H. Dem...


LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
SLOAN'S
N & B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Tender Feet
Toothache
Keep away from
Fire or Flame
TO
STOP YOUR
ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd. London.
England
Carton adopted 1916.
FASSETT & JOHNSON,
Road, London, E.C.
ST. LOUIS. TORONTO. CAN.
BOSTON
in United States of America

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RE.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

E fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

KILO NDA WỌN LỌNA?

Ni koi pẹ yi ni a gbọ pe awọn kan pa'nia meji lọna Idi-oro, tobẹ ti ẹru-jẹjẹ fi mu ẹnikẹni ti o gbọ irohin yi, ewu kekere kọ ni a gbọ pe o wa lọna oko fun ẹniti o ba ndarin papa ni werewere oju alẹ. Eyi ma ṣo ni lọwọ o.

GBAJARE APA'NIA O!

Awọn Ọlọpa fi iwe si'a pe awọn yio san pọnuh mẹwa fun ẹnikẹni ti o ba le ri ọkọnrin kan ti o njẹ John Otulagbe ti o pa aya rẹ si ikorita Clifford Road, Ebute Mẹta, lẹnu oṣu bi meji to kọja fun wọn.

AGBO LO ṢORO L'ỌJỌ ILEYA.

Ọgọrọ agbo ni o nwọ ni opopo ode nisisiyi, eyiti o fihan pe Ileya nku fẹfẹ: ẹniti ko ni ipa agbo rira ko ni ṣe ki o maṣe ri ẹran Ogunfe tirẹ ra. Akoko yi ni awọn obinrin ile nma nmura ati se "kọtọ" ọpọlọpọ ati ọbẹ aladun miran.

GBERE ỌMỌ OLOWU.

Ọgbẹni Charles O. Olowu de si Eko lati ilu Ibini lẹnu ọsẹ meji sẹhin lati wa ṣe kokari iṣẹ ribiribi ti o nṣe ni ilu na, o si pada lọ ni *Wednesday* ọsẹ yi.

Ẹ KU ORIRE.

A ba Ọgbẹni P. St. Mathew Daniel yọ fun igbega ti a tun gbẽ ga lẹnu iṣẹ rẹ ni lọlọyi nipa fifi ṣe Olori tabi Ọga awọn akọwe ti nwọn nṣiṣẹ ni Kotu Adajọ Kekere.

Nwọn o ma sọrọ iranti ore rẹ pupọpupọ, nwọn o si ma kọrin ododo rẹ.—Orin Dafidi ori 145 ẹsẹ 7.

*Mr P. St. Mattew Daniel Promoted to Magistrate's Court.*

Editor "Eko Akete"

Jọwọ dakun masai fun mi ni aiye diẹ kiun lati sọ gbolohun oro meji ti o yẹ to si tọ lati so nipa Ore opọlọpọ ti Ọgbẹni wa Mr. P. St. Mattew Daniel ṣe nibi iṣẹ rẹ. Ka to wa sọ labari diẹ ma mu ẹnyin ọkawe irohin *Eko Akete* mọ pe, Ọgbẹni wa yi o tin ṣe iṣẹ labẹ Ijọba ọna re nọ diẹ.

Ni ọdun 1903 o wa ni Judicial Department ni ọdun 1905 a gbe lọ si Badagry fun iṣẹ Deputy Registrar. Ni ọdun 1906 a tun gbe lati Badagry lọ si Shagamu. Ni ọdun 1907 lati Shagamu a gbe lọ si Ijẹbu Ode fun Deputy Registrar ni ọdun 1909 o wa gbe ẹleyin ju ẹgẹ Ọmọ meji iya Ladipo ni iyawo ni ọdun 1910. O wa si Eko lati ṣe iṣẹ Cashier ni Kotu nla Ni ọdun 1926 a wa da ni Ọla Oye Registar ti ọdọ Ọya. Ni ọdun 1928 a tun gbe lọ si Kotu kekere fun ipo Registrar ni inu ọdun 1928 ọjọ kẹtalelogun oṣu May a tun fun ni Oye Commissioner of Oaths. Inu wa dun lọpọlọpọ lati sọ pe, Ọgbẹni yi ṣe iṣẹ ni ododo ati tọkọntọkọn tobẹ gẹ, awọn ọmọ to nba ṣe iṣẹ wọn fẹ le sọkun fun kikuro to kuro ni Kotu nla. Ti Ọgbẹni yi, o tun fihan wa lati ma ni suru ati iforiti pẹlu ifarada. Ẹnikẹni le jẹri mi pe Ọgbẹni wa yi o jẹ o ninu re pupọ, o si jẹẹni kan to le ṣe iranlọwọ to ba wa ni agbara rẹ fun ẹnikẹni. Ko si Lọya ti ko mọ riri Ọgbẹni wa yi Adajọ papa sọ pe, anu ṣe mi lati fi ọ silẹ. Ṣugbọn iranlọwọ ki iranlọwọ to ba fẹ emi yio ṣe fun ọ pẹlu inudidun. Ni da keji ẹwẹ awọn ọmọ iṣẹ rẹ bi mẹta a bi mẹrin tun gbarajọ wọn fun ni iwe ọrọ didun ati iṣiri fun iranti ati fun ọtẹ rẹ larin won. Gẹgẹ bi ati gbọ irohin rẹ lati ẹnu nkan ninu akọwe Kotu nipe bi iru ọga bayi ba le pe meji ni Office kan ẹni kan ko ni mọ ẹmi lẹ mi. Eyi yi a rope yio jẹ aperẹ iwa fun awọn ọga ibi iṣẹ iyokvn.

Nitori eyi la ṣe rope o yẹ o si tọ lati sọrọ iranti ati ore rẹ pupọ. Mo dupẹ fun aiye to fi fun mi o. Abẹ ifari rẹ ko ni kú o. Idigbolu Ọba ko mi

## DUNIYAN—LABARI.

Lati ọwọ KEKERE AWO.

### O DABỌ O !

Ọlọla Gomina Graeme Thomson, K.C.B., ati awọn Ikọ rẹ da an lọ si irin-ajo lọjọ kẹtadinlogun oṣu yi, a si tanma pe yio de titi ojọ 21 oṣu yi kanna. yi :—ọna 're o...o.

### ERE KI BA 'YI WA ?

Otitọ ha ni labari ti a gbọ wipe o ṣẹlẹ pe awọn ọkunrin kọngbọn-kọngbọn meji (Alimi ati Sanni kọtun wọ igbotogan ni Idoluwo leti ile oloye Ọbanikoro lẹnu ọsẹ meji ? bi o ba jẹ gasikiya, ayo tabi kinla ?

### SALAMU-ALEIKUN !

A gbọ wipe awọn Imale "Gbẹbọ" lọ ṣe "Suna" ifi orukọ fun ọmọ larin ọsẹ to kọja ni ile kan ni adugbo Oluwọle, nwọn fi oruko fun ọmọ tan; nwọn ṣe adura ti Imale nṣe fun Baba ati Iya ọmọ ati awọn ara ile gbogbo ; Ṣugbọn nigbati o di ati pin kọbọ owo-sara, akara tu si epo, awọn aladugbo ko tẹ 'ti lelẹ ki nwọn to mọ ohun ti nwọn se ki ina to jo, ariwo ati ijakadi ni nwọn fi tuka lọ si ile, jam ! jam ! ! jam ! ! !

### ỌRAN MASUWỌN KO MAṢE TOJU ẸNI ṢẸ.

A gbọ wipe Motor L2758 pẹlu oni Basikulu kan ṣe pẹkirẹki ara wọn ni Oluwọle Street, lojude Alaji Yuṣawu lowurọ ọjọ Satide to kọja, kẹkẹ-ologere na fi ara gba, diẹ lo ku fun oni-Basikulu papa ko lugbadi agbako moto na : A bẹ ẹnyin awa-motọ (*Motor Driver*) kẹlẹklẹ dọwọ nyin, nitori ohun kekere lo nṣọ 'ṣẹ.

### LAGOS TOWN COUNCIL.

A gbọ wipe awọn Alatunṣe-ilu ko bun wọn ni aye lati ṣe Busọ ti nwọn ṣe si Gbangba Anikantamọ bi o ti wu olukuluku—irufẹ ede bẹ ko ye wa ẹrara, enia haya ibikan o si nsan owo fun ibẹ alalikuwa ki iṣe lọfẹ, ofin irufẹ wo ni eyi o? bi oluwarẹ tilẹ tun ibiti o haya ṣe, ṣe oluwarẹ lo ni owo to fi tun ṣe ki iṣe wipe boya adehun wa wipe iye ti oluwa rẹ ba fi tun ibẹ ṣe ẹniti o ni nkan yio da owo rẹ pada—bi a ti gbọ si ni a sọ yi, bi o ba jẹ bẹ, ofin ti awọn Alatunṣe-ilu nlo nipa eyi pe nwọn kogbọdọ ṣe ohunkohun sinu Busọ ti a wi yi lẹhin eyi ti awọn Munisiba ba ti fi ọwọ ara wọn ṣe si bẹ ko ye wa.

Irufẹ Busọ na ha ni irọrun lati lo laseko ojo ?

### MUNISIBA ATI BUSỌ.

A tun gbọ finrin nisisiyi wipe owo ti tun gun ori Busọ ti Munisiba ṣẹṣẹ ṣe si Oke-arin ; nwọn ni ṣile marun ni awọn ẹniti o ba nta Ilẹkẹ yio ma san, gasikiya li eyi lati keri a ?

### AFỌJU ALUMỌNGERI PẸLU AWỌN ỌMỌ-EKO.

Ni alẹ ọjọ ọsẹ ọjọ 20 oṣu yi, a gbọ wipe ija kan ṣẹlẹ larin Afọju Alumọngeri pẹlu ọmọdebinrin kan ni Palm Church Street lọkankan ile iṣẹ Lọya Coker : ohun ti nwọn sọ fun wa pe o bi ija yi ni wipe, ọmọde-binrin kan gbe apandi-panu dani ni iwọn owo sisi (6d.,) o sọ fun Alumọngeri na pe on fẹ ṣe sara kọbọ kan fun u ki o mu ṣengi kọbọ marun wa, Alumọngeri ni ki o mu owo na wa ki on fun ni ṣengi rẹ, ọmọde-binrin na gbe apandi-panu na fun u, Awusa Afọju na fi oye wo ohun ti ọmọ na fun u, o ri wipe ki iṣe owo tara, Afọju na ko ṣopo ṣe meji gbagi lo mu ni aṣọ dani, o gba aṣọ lara ọmọ yi,

O wa di ritiriti gbogbo enia nbere bo ti jẹ, ọmọ ko ẹjọ o ro, Afọju ro tirẹ, gbogbo enia bẹrẹsi da ọmọbinrin na lẹbi, nwọn bẹrẹsi bẹ Afọju pe ko *ya ankuri* ki o da aṣọ ọmọ pada, ibinu eyi ko jẹ ki Afọju fẹ da aṣọ pada mọ, o wa di kirakita awọn ọmọ Eko pẹlu nwọn fẹ gba aṣọ lọwọ Afọju lagbara, Afọju bẹrẹsi na igi mọ wọn gbau-gbau-gbau, ti Afọju to bẹ o ju bẹ lọ, ekini tani fẹ ki on wa ni irufẹ ipo bẹ ? ekeji ko si ibẹru Ọlọrun lọkan awọn ọmọ-Eko tun fẹ gba ti ọwọ Afọju ti o nṣe domi-Allah-domi-Anabi ; a mokun-kun ṣole bi Ọba aiye ko ri ọ tọrun nko ? i ba ma jẹ wipe Awusa Afọju yi fi oye si owo ti nwọn gbe fun bẹni awọn ọmọ Asaba yi i ba ṣe ọgbọn gba owo lọwọ Afọju.

A si gbọ wipe awọn ọmọ Eko ti nṣe bẹ o ti pẹ, ẹ bẹru Ọlọrun o, fun gbogbo ẹniti o ba nṣe irufẹ iṣe buruku na.

Ẹniti o ba nfẹ ta Alumọngeri lọrẹ owo ki oluwa rẹ lọ wa owo rẹ ṣẹ ni-bomiran, bi o ti tọ loju wa ni iyẹn o.

### AWỌN MỌTO ATI VICTORIA ROAD.

A gbọ wipe ọpọlọpọ Mọto ti Ijọba dari wọn si ọna Martins Street tabi Balogun Street lati ma gba dipo Victoria Road, nigbati opopo na di fun iṣẹ atunṣe titun bẹrẹsi rin lati ọjọ Monday ọsẹ yi, awọn olori ọlọpa lo ti yara fun wọn ni aye yi ni tabi adabowọ awọn awa-mọto tikalara wọn ? Gẹgẹbi o ti jẹ wipe o wu wa ki Ijọba ṣe eto pataki fun Victoria Road nitori awọn ọpọlọpọ jamba ti awọn moto wọnyi nṣe enia.

### ỌDUN ILEYA DE.

Oṣu ti awọn Musulumi npe ni "*Zulhadji*" yo si oju ọrun ni alẹ ọjọ Sunday ijeje, Ọdun Ileya ku ọjọ mọkanla, ṣugbọn loni Satide ọjọ marun lo o ku nitori ipari oṣu yi gan li a gbọ wipe nwọn yio kirun, nitorina a ki gbogbo Imale patapata, nwọn ku ipamọ Ọdun o, ki Ọlọrun ṣọ gbogbo wa di

igba na ki o si bo olukuluku nyin ni aşiri ẹran-agbo ti ẹ o pa lọjọ Aluruba, papa Ẹgbẹ Dẹmọ ki ẹ ranti ẹran ti wa o, lẹhinna gbogbo ẹniti Ọlọrun ba ti yonda ẹran fun, ki ẹ şe abojuto daradara ki awọn alada-nla ma fi ada wọn şa nyin.

EJO SARE IKU LAGBA-LAGBA.

Obinrin kan sare bi kannakanna ni Victoria Road nibi Şabu awọn oyinbo Alagbọn, lọjọ Monday ijẹfa nigbati awọn mọto meji kan fẹ pobiriko-to le obinrin na lori, koda diẹ şiun lo ku fun u, ori to yọ obinrin na ko kere, ti o ba ni ẹran nile ki o lọ fi bọ ori rẹ na ; şugbọn ẹsọ ko to owọ ẹnyin ọmọ-ọjẹka papa bi a ti nkigbe fun nyin yi o.

ỌJỌ-IBI ỌBA.

Ọjọ-ibi Ọba Queen Victoria pe lọjọ 24 oşu yi gẹgẹbi işẹdalẹ awọn ọmọ Ile-Ẹkọ ti Kiriyo ati ti Imale lọ yọ fun Ijọba l'ọdun, Gomina ti de, on ati Oyinbo Ọlọla H. M. M. Moore, Igbakẹta rẹ, li a ro wipe yio lọ si ọdan. Ki Ọba King George ko pẹ.

DUNIYAN-LABARI !

Ni ọsẹ yi a toro gafara lati sọ fun ẹnyin okawe wipe a o bẹrẹsi fi Duniyan Labari eyi yi ni irohin aiye pẹ-pẹ-pẹ şowo si nyin lọsọsẹ, eyi ko si di wa lọwọ fun awọn Wosika pataki ti a ma nşe lọsọsẹ tẹlẹtẹlẹ. o sa wa 'nja li ko jẹ ki a yan fun nyin ni Satide ijẹjọ —lati owọ awọn aiye li a o ti ma ri "Duniyan Labari" wọnyi gba, a ko si bi bikita fun eyikeyi lati gba, nitori fun rere ilu ni ; a ki ẹnyin ilu papa ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ẹ ku aforiti adun lo ma gbẹhin ewuro ; ilẹ fẹrẹ mọ na benbe lo ku o ku benbe !

## The African Church Conference Session, May, 1928.

*May* 6. Conference Sunday. Sermons in all Churches of the Organisation.

„ 13-19 Week of Prayer in all Churches of the Organisation on behalf of the Conference.

„ 22, *Tuesday*, 5 p.m. Evening Prayer and Administration of Lords Supper to Delegates at Bethlehem Church by Rev. G. Mich. Ọşọba.

„ 22, *Tuesday*, 6-9 p m. Conference Session.

„ 23, *Wednesday*, 9 a.m. Conference of Clergy at Bethlehem School-room.

„ 23, *Wednesday*, 5-9 p.m. Conference Session.

„ 24, *Thursday*, Public Holiday 9 a.m.-12 a.m. Conference Session.

„ 24, *Thursday*, 3-6 p.m. Conference Session.

„ 25, *Friday*, 5 p.m. do. do.

„ 26, *Saturday*, 4 p.m.-6 p.m. *a.* Discusson on Lecture by the Rev. E. D. Sodeind "Marriage of the Clergy." *b.* Lecture by Rev. E. A. Obigbesan on "Unlawful Disposal of Church Fund.

„ „ „ 7 p.m. Light Refreshments to

„ *Whit Sunday*, 9 a.m. Joint Service at Bethel Church, Lagos, Pracher: Rev. D. H. Kukei.

„ „ „ Joint Service at Bethlehem Church Ebute Meta, Preacher: Rev. Sotayo Williams.

„ „ „ 4 p.m Special Thanksgiving Service at Salem Church, Preacher : Bishop J. A. Lakeru.

P.S. *All Conference Session will be held at Bethlehem School, Ebute Meta. All collections on Conference Sunday should be devoted to Conference Fund.*

A. Olumide,
S. O. Ilori'
*Conference Secretaries.*


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oşupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le şẹşẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Şango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Orişi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Şabu Oyinbo Kessler ni No. 7, Labinjọ Lane.

**Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maşe gbẹhin ki ẹ to ranşẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.**

## EKO AKETE

EKO, SATURDAY, MAY 26, 1928.



### "NIBO L' Ẹ WA, T' Ẹ NRANṢẸ S'ARA 'LE?

Kika ti a ka Akanṣe Iwe-irohin Ijọba ti ọjọ kẹrindilogun oṣu yi lo mu ni ro pe ede ti Ijọba nlo si awa ara Eko niyi, papa ni ti aṣẹ Ọba King ti a sọ pe Gomina Agba ri gba lati tubọ fi enia kun Ajọ Igbimọ Aṣofin ti Ijọba. Irufẹ fifi kun bayi ki ṣe pe yio ti ọwọ awọn ti o to dibo fun Ajọ Igbimọ Aṣofin wa, agbẹdọ, iba enia mẹta ti Gomina Clifford yọda niwọn ọdun karun wa ni a si nlo titi di oni: ko si bi awọn agbagba ti nwọn mbẹ nidi ọrọ ilu ko ti ke pe enia mẹta pere ti Ijọba yọda fun Eko lati ran wa si Ajọ Igbimọ Aṣofin Nigeria ko de ibi kan, ṣugbọn sibẹsibẹ ko si atunṣe kan ti iba mu ori ilu wu, kaka bẹ nṣe ni ofin ti n fun Gomina isisiyi lagbara ki on papa le yan ẹniti o ba fẹ bi mẹta kun awọn ti Ijọba ti yan fun ara wọn ninu Ajọ na.

Nipa aṣẹ Ọba King ti a ti nsọrọ rẹ yi, awọn ti yio jẹ Aṣoju Ijọba ninu Ajọ Igbimọ Aṣofin na ko ni ṣa. gbe awọn Aṣoju Eko mẹta mi t'awọn pẹlu awọn Oyinbo Aṣoju Oniṣowo ati iṣẹ miran: ewu ti a si ro pe o mbẹ fun titayọ ti awọn Aṣoju Ijoba ta awọn Aṣoju Eko mẹta yi yọ ati awọn Oyinbo Aṣoju Òwò ni pe ipa ni ẹnu awọn Aṣoju Eko ati awọn Oyinbo Aṣoju wọnyi le fi to'lẹ fun ofin kofin ti awọn Aṣoju Eko ati awọn Oyinbo Aṣoju miran le ro pe yio jẹ inira fun ilu: nitotọ a mọ pe olukuluku Oyinbo ati Enia Dudu Aṣoju Ijọba ni nwọn le dibo gẹgẹbi o ba ti la si wọn lẹkan, ṣugbọn ohun ti o wa nibẹ ni pe tani ẹniti a pe sipo ọla lati wa ba ni ṣe aṣaro lori ọrọ ilu ninu Ajọ Igbimọ Aṣofin, yio ma gbe fun bikoṣe ẹniti o pẽ lọ sinu ijọ ọla bẹ tani eṣinṣin iba gbe? A ro pe gbigbọjẹgẹ ti Ọba King gbọjẹgẹ fifi aṣẹ fun Gomina Agba lati fi enia bi mẹta kun awọn Aṣoju Ijọba ninu Ajọ Igbimọ yi, ki iṣe ẹhin Gomina nibi, ati suke ko le ṣẹhin lakuregbe; Ọba King ko mọ ohun ti Eko nṣuta de ipo pe ki o fi ka si ohun ti o yẹ ni ṣiṣe fun Gomina lati pa laṣẹ fun ki o tubọ fi ẹni bi mẹta kun Aṣoju Ijọba ninu Ajọ Igbimọ: Ijọba lo lọ si Ọyọ ti o si t'Ọyọ bọ.

Niwọn igbati Gomina ba ṣi ni agbara lati ma fi enia kun Ajọ Igbimọ lati ṣe iranlọwọ fun Ijọba, njẹ kini kõmi Aṣoju mẹta pere ti a yọda fun Eko lati ọjọmọjọ yi wà. Nibo ni Eko wa ti o nranṣẹ si ara 'le: ki lo tun le da Gomina lọwọ duro lọla ki o ma tun le fi gba aṣẹ Ọba King lati tun fi bi enia kun Ajọ Igbimọ lati pẹlu ogunlọgọ awọn Oyinbo Oniṣẹ Ọba ati awọn Enia Dudu ti nwọn mbẹ nibẹ fun ṣiṣe oju Ijọba: ohun ti a ro pe o yẹ fun ilu ni pe ki awọn ma ṣalai fi irufẹ titẹ ti ọkọ yi ntẹ sapakan yi han, ki nwọn si ṣe kokari ati sọ fun Gomina ki o maṣai jọwọ ba ilu Eko gba aṣẹ lọdọ Ọba King lati tubọ fi bi enia mẹfa kun awọn Aṣoju Eko mẹta ti o wa nisisiyi; gẹgẹbi a ti sọ ni iṣiwaju, bi Gomina yan Ọgbẹni Ọdẹyẹmọ Onikija lati jẹ ọkan ninu awọn Aṣoju Ijọba, tani irufẹ Ọgbẹni bẹ le fẹ gbe fun nigbamiran bikoṣe Ijọba: bi o ṣe iwọ nkọ, talo ba ma saba a ngbe fun? A ko kun si eyi, ṣugbọn ohun ti ilu nwi pataki ni pe awọn Aṣoju Ijọba ti pọ nj apọju tobẹ ti o jẹ pe iye awọn Aṣoju Eko ati awọn Aṣoju miran ko de ibi kan: ọkan ninu ọrọ pataki ti o wa ninu Akanṣe Iwe-irohin Ijọba na ni eyi, o si ya ni lẹnu lati gbọ pe bamiran ni awọn ope-aperun kan pẽ fun awọn enia tobẹ ti irọkẹkẹ nipa iwe na fi gbilẹ; a ya bara si eyi ni fun eti igbọ awọn ti nwọn joye akọwe Alagbọn, a ṣe ko mọ'we!!!

A bẹ Gomina, ko dakun, ki o fi aroye gbolohun mẹji mẹta yi si ero.

Ki ọtun wẹ osi,
Ki osi wẹ ọtun lọwọ fi nmọ.

## EJỌ ELEKO LATI NIGERIA.

Kotu abẹṣẹ Ọba *King* eyiti awọn Onidajọ Lord Chancellor, Lord Buckmaster ati Lord Wrrrington gbọ ẹjọ Eṣugbayi Eleko ni *Monday* nipa eyiti Kotu Arotunro Eko da ti, nigbati Tew igbakeji Adajọ Agba sọ wipe on ko ni aṣẹ lati jẹki Ijọba da Eleko pada wa lati Ọyọ.

Ohun ti Tew sọ ni pe on ko ni agbara lori ọrọ ti Kotu ti takulẹ eyiyi ni mimu Eleko pada wa lati Ọyọ, ẹnikẹni ti a mu ni imu aitọ le kọwe si Adajọ Kotu Ganran, ki o si gbẹkẹle iwe Hulsbury ti a npe ni Laws of England lati mọ idi fifi ni si ẹwọn ti a fi ni si ẹwọn, ti Adajọ kinni ba kọ lati yẹ iwe na wo, oluwarẹ ni ẹtọ lati tun lọ si Kotu omiran ti o ba ro pe o yẹ lati tẹ ararẹ lọrun.

Adajọ Tew sọ wipe Kotu Ganran le jẹ meji l'Eko ti nwọn joko pọ lati ṣiṣẹ lẹkanna, ati pe Adajọ ni isi joko si Kotu kan, Kotu Ganran kan lo si mbẹ ni Nigeria, nitorina o ni on kole tu nkan ti Onidajọ omiran ti sọ palẹ ati Kotu Aroturo nikan lo to iyẹn ṣe, o si ka iwe-ofin kan Boury (2) 18, New Zeland, iwe 16.

Nigbati Kotu Ganran ba kọ lati yọnda mimu ẹniti a fi si ihamọ wa si Kotu lati sọ ti ẹnu rẹ, iwe miran ti a ṣe fun nkan kanna kole muro ni Kotu na.

Ni August 6, 1925, Ọgbẹni F. M. Baddeley ti di Oloye Sir nisisiyi, ti o si jẹ Alaṣẹ Ijọba nigbana pa aṣẹ pe ki Eleko kuro ni Eko ati Igbereko Abẹokuta, Ijẹbu-Ode ati Ondo, ki o ma si pada wa lai si aṣẹ on, Baddeley si sọ wipe Eṣugbayi jẹ Oloye ti a npe ni Eleko, o si jẹki a wa lọ si Ọyọ.

Eleko sọ ti aitọ ti a fi kan on bayi, gẹgẹbi Ọmọ-abẹṣẹ Ọba King; Kotu ti kọ iwe ti o ti ṣe lẹkanri nigbati kosi ibura mbẹ, iwe ti Eṣugbayi ṣe si Adajọ fihan pe Ofin ti a lo fun on ko ba on wi, nitoripe on ki iṣe Oloye gẹgẹbi Ofin na ti wi, Eleko ni ẹnikẹni ko rọ on loye ati pe Ijọba ti dawọ kika on si gẹgẹbi Olori Ile Dosunmu duro lati oṣu December 1, 1920, nitori eyi Ijọba ka on si enia ṣapala.

Ọgbẹni E. F. Hunt ti o ngbe 6 Gray's Inn gba Lawyer Montgomery K.C. ati Horace Douglas fun Eṣugbayi Eleko, awọn Ọgbẹni Burchells ti No 5, Sanctuary gba Ọlọla Stafford Cripps K.C. ati Sydney Pocock ati J. G. Howard Igbakeji Agbẹjọro Ọba Nigeria fun Baddeley Oloye.

Ọgbẹni Montgomery taku wọnle pe ni iwọn igbati Eṣugbayi ti kan si Tew Adajọ, Adajọ na ni lati gbọ ti ẹnu rẹ ati pe kiko ti Adajọ Tew si kọ nitoripe iru nkan bẹ tilọ si iwaju Onidajọ Webber ri ko jẹ ohun ti o tọ suna, kosi jẹ ohun ti o tọ suna pẹlu lati kọ iwe Eṣugbayi bi Adajọ kan ti gbọ ẹjọ na ri bi koi ti gbọ ri, Lawyer Montgomery sọ wipe awọn Onidajọ ko gbọ ẹjọ na bi o ti tọ, ohun ti Adajọ Tew sọ ṣapala ni pe, Idajọ ile awọn Ọlọla, eyiti o le mu Eṣugbayi lọ lati ọdọ Adajọ kan si ekeji ninu Kotu kanna ti Ganran Nigeria, iwe meji ni Eṣugbayi ṣe si Onidajọ Webber ti o ta a kulẹ lai gbọ bi ẹjọ na ti jẹ, ohun pataki ti Adajọ Tew wi ni pe Eṣugbayi ko le lo lati ọdọ Adajọ kan si ekeji ninu Kotu kanna ni Nigeria.

**Lord Buckmaster:** sọ pe itumọ (Hebeas Corpus) jẹ ofin pataki lati ke si ẹnikẹni ti a fi enia pamọ si lọdọ ki o sọ ibiti oluwarẹ wa, ati pe ki ẹniti a fi enia pamọ si lọdọ sọ pe eyini ko tun ṣeṣe mọ, jọ ṣiṣanta ofin pataki yi.

Ọgbẹni Montogomery sọ pe o ni igba ti ẹjọ Eṣugbayi wa si Kotu ati ọpọlọpọ iwe ẹjọ rẹ ti Kotu takulẹ, ṣugbọn ni gbogbo igba yi, kosi igba kan ti kotu ki kotu ṣeṣi yẹ bi ẹjọ na tilẹ ti ri wo, ọrọ ti kotu Nigeria nsọ nigbagbogbo ni pe Adajọ ti tilẹkun ọrọ na.

Ọgbẹni Cripps: sọ pe Webber Adele Adajọ Agba wadi ọrọ na, o si sọ bi o tijẹ loju rẹ.

Lord Buckmaster: Ọgbẹni Montgomery sọ pe ẹ ni ẹtọ lati bere iwe (Hebeas Corpus) lọdọ Adajọ kotu ti a npe King's Bench kan loni ati Adajọ kotu King's Bench miran lọla, awọn kotu ti o mbẹ ni kotu "Common Pleas," Exchequer ati King's Bench, a ti fi ofin kan pa gbogbo awọn kotu wọnyi pọ, ati pe kikuro lọdọ Adajọ kan ninu awọn ẹya kotu wonyi lọ si ọdọ Adajọ miran ti awọn ẹya kotu na, nigbati a pa kotu pọ si kotu giga, o mu ki iye awọn kotu dinku, nisisiyi ẹnikẹni kole lọ ka'ri awọn kotu wọnyi, nitoripe gbogbo wọn lati fi ṣọ'kan, ti o ba jẹ pe iyan jija Baddeley ni eyi, ariyanjiyan na ko ha lagbara bauu? Ti o ba jẹ nkan ti o wọ fun Ọgbẹni Montgomery lati sọ pe ẹnikẹni le lọ sọdọ awọn Onidajọ wọnyi ninu kotu kanna, ko ha yẹ ki o tọka ẹjọ ti a ti ṣe bẹ ri?

Lord Justice Warrington: Kikuro ni kotu lọ si ekeji ko ye mi, ti o ba le lọ si ọdọ Adajọ ki Adajọ Adajọ kan si ikeji ti pari gbogbo nkan, Kotu kan si ikeji le jẹ Kotu King's Bench tabi Kotu Exchequer.

Lord Chancellor: Ẹnu ya mi pe kosi iwe ofin kan pataki ti a le mu wa si ọrọ yi, ti awọn ẹjọ miran ba wa, eyiti Ọgbẹni Montgomery le muwa titi ọla, inu mi yio dun lati yẹ wọn wo.

Ọgbẹni Montgomery sọ pe on ko mọ bi on le ri awọn ẹjọ muwa, o ni igbakeji on ti wo awọn iwe-ofin depo, lai ṣiyemeji awọn ẹjọ pupọ bayi le wa ni ilu Canada, ṣugbọn bakan-meji li ọrọ ri.

Lord Chancellor: Ọdun ti a ti da Hebeas Corpus silẹ jẹ adọtalerugba (250) ọdun, o jẹ nkan abami ti ẹjọ kan ko ba si ninu eyiti ẹnikan le ṣe iwe lati ọdọ Adajọ kan si ekeji.

Ọgbẹni Montgomery: Mo ro pe ọpọlọpọ ẹjọ ti wa bẹ, ohun ti o ti wa ninu iwe-ofin ti Lọya nlo fun ọpọlọpọ ọdun, jẹ nkan lilo lati lọ lati ọdọ Adajọ kan si ekeji; ninu nwọn nsọ yi tan, ni ẹjọ sun di ọjọ Tuesday ọjọ keji rẹ.

Ni ọjọ Tuesday, Ọgbẹni Montgomery sọ wipe ẹjọ ti Barnardo 1892, jẹ apẹrẹ irufẹ iwe bẹ, ikan si Adajọ ekeji si kotu ti a npe ni Queen's Bench.

Ninu iwe-ofin Parkington 13 Meeson ati Welsby Page 679, ọgbọn ọdun ṣaju siso ofin dida Kotu pọ ti 1873, Baron Parke sọ pe, ẹjọ na ti wa si iwaju Queen's Bench ati si iwaju Adajọ Agba ni Gbangan kotu, nigbati a tun kọwe lẹnkeji fun irufẹ aṣẹ bẹ, kotu kọ lati dahun si iwe oluwarẹ lẹmejeji. Ẹniti a nba ṣe ẹjọ ni ẹtọ lati lọ si kotu kan si ekeji, nipa bi fifi si ẹwọn ti a fi on sẹ'wọn to, nitori na, a ro pe o yẹ lati wadi ofin daradara lalai fi tiwa kun un. Iwe ẹjọ ti a npe ni Cox V. Hakes 1890, lẹhin siso ofin dida kotu pọ, Lord Halsbury sọ nile awọn Ọkla pe, " ti a ko ba da ẹniti a daduro na silẹ oluwarẹ ni ẹtọ (gẹgẹbi o ti wa ninu iwe-ofin ẹjọ Parkington) lati ṣe iwe si olukaluku Onidajọ ati si olukuluku kotu, nwọn si ni yẹ ọran na wo gedegbe lai jẹki ẹjọ omiran ti o kọ dida-silẹ ẹniti a mu lọna yi di wọn lọwọ. "

Ọgbẹni Montgomery sọ pe itumọ Kotu ti a nwi ki iṣe Kotu Qeens Bench, ninu eyiti gbogbo awọn Adajọ wa ni orişirişi Kotu wọn, ninu eyiti a le yọ iwe ti A ba ṣe si B. C ati D. itumọ rẹ ni pe Adajọ ti o ndajọ ni Kotu eyiti o yatọ si Onidajọ ti o joko ni ile rẹ tabi ninu yara iwe rẹ, iyatọ ti o mbẹ larin Kotu Queen's Bench, Common Pleas ati Exchequer jẹ iyatọ larin awọn Adajọ ti o joko ni Kotu ati pe a lo ohun ti a pe ni Adajọ lati fihan pe a le ṣe iwe si Adajọ ni ile rẹ tabi ni yara iwe-rẹ, iyatọ ti o ti wa ni iyen fun ọpọlọpọ ọdun. Lord Herschell ni iwe ẹjọ Cox ati Hakes sọ pe, bi ẹnikan ti a takulẹ ni Kotu kan ba fẹ, o le mu ẹjọ rẹ lọ si Kotu miran, kosi Kotu kan ti Kotu ẹgbẹ rẹ le dilọwọ nipa ọran na, ẹniti a fi si ipamọ le lọ lati Kotu kan si ekeji titi yio fi ri ominira ararẹ; kosi ẹnikẹni ti a le fi si itimọle ti kan ninu awọn Kotu wọnyi ti o lagbara Ofin Habeas Corpus, ba sọ pe irufẹ itimọle bẹ ko tọ suna."

Lord Herchell nsọ ti Kotu kan pẹlu Adajọ ati Kotu miran pẹlu Adajọ miran.

Lord Buckmaster: Nigbati iwo ba lọ lati ọdọ Adajọ kan ninu Gbangan rẹ si ọdọ Onidajọ keji sinu Gbangan rẹ Kotu kanna lo nṣe.

Ọgbẹni Montgomery: Lati ọdun 35 ni a ti nṣe irufẹ nkan bayi firifiri; iyoku kere.

Lord Warringhton: njẹ kotu ti a npe ni Judicature ha jẹ ọkan bi, ninu eyiti Kotu giga jẹ ẹka rẹ? ti o ba jẹ pe bẹ ni nkan ti nisisiyi pẹlu awọn kotu, ko fun ẹnikẹni laye rara lati ṣe irufẹ iwe bẹ, iyẹn ni pe lati lọ lati ọdọ kotu kan lọ si ekeji.

Ọgbẹni Montgomery: O di enia lọwọ lọna ti Lọya kan ko mọ ri ni ilu nibi, ko ri bayi ni Canada, iyatọ ti o mbẹ larin Adajọ ati Kotu kan je iyatọ larin Adajọ ti o joko ni Gbagan ile rẹ ati Kotu, ati pe lilo lati ọdọ Adajọ kan si ikeji jẹ pe lati ọdọ Adajọ kan ti o joko ni kotu lọ si ọdọ Adajọ miran, ki iṣe ti awọn ẹya kotu li a nsọrọ le lori.

Ọgbẹni Montgomery nba ọrọ miran lọ nigbati Lord Buckmaster sọ pe ohun ti a ni lati mọ ni pe ohun ti awọn apakeji nja fun ni pe Eşugbayi ti bere ofin *Habeas Corpus* şugbọn a ko fun, ohun ti o tun tẹle eyi ni pe Kotu ko tun ni lati gbọ nkan ti a pati, egungun ti o ti fọ tu-tu ni iyẹn; ti awọn Adajọ Kotu Nigeria ko ba gbọ bi ẹjọ na ti ri, awa kole gbọ nihin, a le sọ pe, nwọn ti gbọ lẹkan ri, şugbọn ki iṣe kotu keji ti a tun kan si lo gbọ, ti a ba jẹ ọ lohẹn' iwọ na fẹ ki a tun da ẹjọ na pada, si ọdọ Adajọ Tew lati tun gbọ?

Lord Chancellor: gan lẹru ẹjọ na ni iyẹn ko si fifi ọrọ bọpo-bọyọ mọ, ti ohun ti Adajọ Tew ba sọ ba tọ, njẹ o tọ na ni iyẹn, bibẹkọ a o da ẹjọ na pada si i.

Lord Buckmaster: Ariyanjiyan iwọ Montgomery dabi ẹrọ afanja ti o nti 'nu ja s' ode.

Ọgbẹni Cripps: Lọya Ijọba wipe ohun ti on sọ ni pe nwon ti yẹ ẹjọ na wo gẹgẹbi o ti tọ.

Lord Buckmaster sọ pe yiyẹ ẹjọ na wo ki işe ọrọ ti Privy Council nihin, ti Eşugbayi ba jare ẹjọ yi a o da ẹjọ na pada.

Ọgbẹni Cripps sọ pe on şebi Ọgbẹni Montgomery sọ ọrọ yiyẹ wo lati fi şe Privy Council ninu ni; ki işe ọrọ ofin, ọgbẹni Cripps tọka si iwe ti Blackstone şe fun itan orişirişi kotu ti nwọn ni agbara ofin, ohun ti o sọ pataki nibẹ ni pe nipa yi yẹ ọrọ Adajọ ati Kotu ti o ba jẹ wipe Kotu Queen's Bench fẹ gbọjẹgẹ fi funni ni iwe-aşẹ *Habeas Corpus* ba şe pe kotu na wa ni isimi tabi lẹnu işẹ: ni igba isinmi ko si Kotu Common Pllas ati Exchequer, a ko le sọ pe Kotu Queen's Bench ati Kotu miran ko le mu aşẹ wa nigbati nwọn wa ni isinmi; ni igba isinmi ẹnikan ni adugbo ti a npe ni Brighton, bere aşẹ yi lọdọ Adajọ kan (Kotu ku sẹrin)

Lord Chancellor: ti Adajọ na ko ba si mu wa njẹ iwọ yio lọ si ibiti a npe ni Eastbourne (Kotu ku sẹrin.)

Lord Warrington: Itumọ Kotu jẹ ibi gbayawu fun ẹjọ dida, itumọ Adajọ jẹ enia ti o ndajọ.

Ọgbẹni Cripps: Kotu jẹ ibi gbayawu fun idajọ, eyi yi ni awọn Adajọ ti o ndajọ ni kotu, ohun ti a nsọ ni ti gbayawu ti kotu jẹ.

**Ọrọ ti o wa ni pe ẹtọ ti ẹnikẹni ni, lati lọ si kotu nigbati o mbẹ lẹnu işẹ ati si ọdọ Adajọ ni akoko**

isinmi ko si ohun ti o fihan pe ọmọ-abẹṣẹ Ọba kan ni ẹtọ lati lọ si kotu kan lẹmeji, ohun ti Eṣugbayi sọ ni pe on ni ẹtọ lati lọ si kotu kanna lẹmeji, lẹmẹta tabi lẹmẹrin.

Lord Buckmaster: Ẹ jẹ ki a wo o lọna ẹniti o wa ni abẹ Ọba Alaiyeluwa, emi ko ri iyatọ ti o wa larin lilọ si kotu kan lẹmeji tabi lilọ si awọn kotu miran ti nwọn ni agbara ofin bakanna, ti Eṣugbayi ba ni ẹtọ lati lọ si kotu ti o ni aṣẹ ofin kanna, o jẹ ohun ti o ṣe mi loju su u, pe ki ẹtọ na ki o pora ẹto tlan-tian ni, ẹtọ lati tun gbidanwo ohun ti a ti ṣe ri ni.

Ọgbẹni Cripps: Mo gbadun ọrọ ti ẹ sọ yẹn, ofin dida kotu pọ ti din ẹtọ na ku.

Lord Buckmaster: sọ pe on lo le ri si pe ti enia ba lọ lati ọdọ Onidajọ kan ni Gbangan rẹ si Kotu iyẹn jẹ ti ofin ti ko fi ara gbun ohunkohun, Adajọ Kotu Exchequer ti o wa ni isinmi nfi ọwọ si we gẹgẹbi Adajọ kotu Exchesquer, sibẹsibẹ Ọgbẹni Cripps ni ki iṣe kotu na.

Lord Chancellor: sọ pe ọrọ labẹ aṣẹ 14, ti kotu giga le mu ki a fọwọ si iwe tita ẹrù enia.

Lord Buckmaster: Adajọ ni lati ma lo aṣẹ kotu; o jẹ ohun ti o le lọpọlọpọ ti o ba jẹ pe nitori ofin dida kotu pọ, ẹnikan du ọmọ abẹṣẹ Ọba ni ọkan ninu awọn ẹtọ rẹ, ṣiwaju ofin dida kotu pọ, o le lọ lati kotu kan de ekeji, isisiyi ko le ṣe bẹ mọ, a sọ pe o jẹ nkan pataki lati dabo bo awọn enia ni ọjọ wọnni, nigbati awọn Adajọ ko da wa tobẹ gẹgẹbi nwọn ti ni lati da wa, o jẹ ẹtọ iyebiye, o si jẹ ohun ti o ṣọ ni lọwọ lati ri pe ofin dida kotu pọ fi ẹrọ ja ẹtọ yi gba lọwọ enia, nitoripe ko ṣe ja gba tarata.

Ọgbẹni Cripps: Ti iwọ ba ni ẹtọ lati lo lati kotu kan de ekeji ti o si da awọn kotu wọnyi pọ, ẹtọ na ko si mọ, ọna pupọ wa, lati dabobo ẹniti o wa labẹ asia Ọba, ti o ba ta a ti, iwọ le ṣe Apili. Iwọ le ṣe Apili lori kikọ ti a ti kọ iwe rẹ, ohun ti Eṣugbayi iba ṣe ni'yi, a si sọ pe Eṣugbayi iba ṣe iyẹn.

Lord Buckmaster: Ti ẹtọ lilọ si Kotu de Kotu yi ba wa, ati awọn Kotu ti nwọn ni aṣẹ kanna, ẹtọ yi ko si mọ, ti ẹnikan ba si lọ sọdọ Adajọ, o jẹ ohun ti ko ye mi lehin igbati nwọn da Kotu na pọ idi rẹ ti ko fi le lọ si ọdọ awọn Adajọ meji ti nwọn ni agbara kanna.

Ọgbẹni Cripps: O lọ si Kotu; o le jẹ Kotu afẹnupe, ṣugbọn iyatọ na jẹ pataki, ọrọ ẹjọ ti Loo hen No. 2 ti a ṣe, o sọ ọrọ ẹjọ ti Montgomery mu wa di oku, nitoripe ẹjọ na so pe bi o tilẹ jẹ pe enia le lọ lati Kotu de Kotu lẹkan fun idasilẹ, ki iṣe lati ọdọ Adajọ kan si ekeji ti Kotu kanna, ni iwọn igbati a ba ti da gbogbo Kotu pọ, ko si ẹtọ lati lọ mọ lati ọdọ Adajọ kan si ekeji, nitoripe idajọ ti ọkan ninu awọn Adajọ wọnyi ba ṣe ni abẹ ge.

Lord Buckmaster sọ wipe on ṣiyemeji si ohun ti Cripps wi, eyiyi ni pe ko si Kotu ni iɡba isinmi. Ajọ Igbimọ nla ti Ọba wa ni igba isinmi, Kotu si wa lọjọ *Sunday* ni ẹnu iṣẹ nigbati Kotu wa lẹnu akoko iṣẹ.

Ọgbẹni Cripps sọ pe Kotu Igbereko wa ni o ni agbara lati fun Eṣugbayi ni aṣẹ *Hebeas Corpus* yi, Kotu ti o nwi ni ti Ọyọ, nibi ti a gbe fi pamọ si, Eṣugbayi iba ṣe iwe lọ si ibẹ.

Lord Buckmaster sọ pe Eṣugbayi ni ẹtọ lọna itan ofin lati tun iwe rẹ ti a kọ ṣe, o ni lilọ si ọdọ awọn Kotu fun aṣẹ yi jẹ ẹtọ ti o ti wa fun ọmọ-abẹṣẹ Ọba King lati ọpọlọpọ ọdun wa, Eṣugbayi le tun iwe rẹ ṣe titi yio fi ri idasilẹ, iyẹn bo jẹ pe o ti ri ri, a ni lati wo ọran na ni iwo ti ọkọnrin ti o wa ni ẹwọn le wo o; ọkọnrin ti a fi si ẹwọn yi lọ si ọdọ A. B. ati C. lati le gba aṣẹ mimu on wa si Kotu lati mọ ohun ti on ṣe ki nwọn to ju on si ẹwọn. o bolẹ, o ri D. E. ati F. nwọn joko, o si sọ fun wọn pe boya ẹnyin D. E. F. yio da mi silẹ, ohun ti A. B. C. sọ ko ri wọn gbe ṣe, mo ni ẹtọ lati tun lọ si ọdọ D. E. F. lati ṣe fitafita si.

Ọgbẹni Cripps: ti Eleko ba ni ẹtọ lati lọ sọdọ awọn Adajọ kọkan, njẹ mo ko igba ẹjọ mi silẹ niyẹn, ti Eṣugbayi ba le ṣe iyẹn, o jẹ nkan ti o ṣe mi loju su pe ko si ẹjọ bẹ ti ati kọ silẹ.

Lord Buckmaster: A ma nkọ awọn ẹjọ bẹ silẹ ti iwuri ba wa to fun kikọ silẹ wọn.

Awọn Onidajọ Ogunna gbongbo si rẹkẹ Idajọ.

*West Africa, May 5, 1928.*

---

## KẸKẸ NIWAJU, ẸṢIN LẸHIN.

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU. ]

Mo bẹrẹ f'oji,

Ero Ijọba ti o gba ẹdẹgbẹrin eka ilẹ, (700 acres of land) lọdun keji sẹhin ni Yaba, lati kọ ẹgbẹrun ile si, lai ti mọ awọn tani, tabi ara adugbo wo li Eko, ni a o ko lọ sibẹ, dabi igbati enia fi Kẹkẹ ṣiwaju Ẹṣin.

Nigbagbogbo ni a ngbọ wipe, Eko ha, Eko ba gadigadi. A ko jiyan wipe bẹni, tabi bẹkọ; ṣugbọn pẹlu gbogbo aroye yi, Ijọba koi fi ọjọ kan sọ tun wa titi di oni-oloni wipe, adugbo bayi, adugbo bayi ni enia ibẹ pọ pupọ ju iye enia ti o ni lati gbe ibẹ lọ. Kaka bẹ, Ọko-elefi kan ko nde lati Ilu Oyinbo lai ko ọpọlọpọ Oyinbo wa si ilẹ yi fun iṣẹ, bẹni Eko ha pupọ!

Loni, Oyinbo pọ tobẹ gẹ ni ibi iṣẹ Ọba ti o jẹ pe ori wọn ni ogidinleje owo ti Ijọba iba fi tun ilu ṣe nrun si. Owo Ibode (Custom Duty) nikan, lai ka owo iwe lori ọkọ wete, lori igi gẹdu, tabi owo

ti Koto ngba lowo awon elejo, ati oniruru ona miran ti Ijoba fi nri owo bi eniti o nda eda, to lati so Ijoba di olola, ti ko ba si inakuna.

Gbogbo ere ti nwon iba je lori işe ti Reluwe Railway) tabi Oko-ile nşe t'o san-t'oru, (aka-fiki, (faka fiki li ojojumo, lati Ido titi lo de Kano, titi de iyano Baro, Jos, Naraguta, Port Harcourt, Enugu, ori-sisan owo işe Oyinbo, ori owo Oko won ni o nfere tan si.

Enia Dudu ko şai ri gba ninn re nitoto, şugbon eyi dabi erun akara, lati ori tabili olowo, ti Lasaru nje ni ojo kini.

Lehin ti awon Oyinbo onişe Oba ba ti gba owo oşu tan, elomiran ngba ogorun ponwun l'oşu, tabi ju be lo; lai ka Duty Pay tabi eni, gege bi eni akara, lori owo oşu, elomiran ngba ogun ponwun l'oşu fun Duty Pay yi, ti nwon ba si ni lati lo si idale, bi Ibadan, tabi ibomiran, lati şe işe bi oşu kan pere nibe, lehin ti nwon wo Oko Reluwe li ofe tan, pelu ile ofe ni Ibadan; lehin ogorun ponwun owo oşu, pelu eni Duty Pay ogun ponwun, ponwun kokan ojumo ni a o tun san fun won pelu, titi nwon o fi pada de ibi işe won pataki ni Eko tabi Ebute Meta

Lehin ti pupo ninu won ba şe ira tabi oraye odun kan ni ile yi lori Enia Dudu ti nwon npe ni Niga (Nigger,) nwon a mu ona Ilu Oyinbo pon ati gba isimi oşu merin tabi marun (alalikua, Hotel ni opolopo won ngbe nibe,) ilu ni yio san owo Oko alo, owo Oko abo: ti yio si tun ma san owo oşu won perepere lohun titi nwon yio fi tun pada wa si ile yi lati paşe fun "Niga."

A ko wipe gbogbo Oyinbo ni oloraye, agbedo! Şugbon ti a ba to Oyinbo jo ni mewa-mewa ni ibi işe Oba, boya ni a le ri meta-meta pere ninu won ti o nşe işe a-şe-kara; pataki işe awon ti o kn ni lati ma fi owo si Iwe-işe ti Enia Dudu ba ti şe yori.

Aiye ti pupo ninu Oyinbo onişe Oba nje, ati ipo ti nwon nlo; Oyinbo onişowo ko ri idaji aiye na je' tabi idaji ipo na lo; beni awon onişowo li o dabi ori, onişe Oba, ati oyinbo, ati Enia Dudu li o dabi agbon, ori li o si duro fun agbon mu'mi

Pelu gbogbo inawo bi oba Peulepe a-l'owo-ma-mo-no ti Ijoba nşe yi, opolopo işe miran wa ti ko ju eyiti Akowe Enia Dudu kanşoşo le şe lo, Oyinbo meji tabi meta ni a o ba ni idi re, ti nwon busy doing nothing.

Ki Akowe Enia Dudu miran to le ri ponwun mefa, şile metala pelu kobo merin gba lowo Oba li oşu, a ni lati koko dan a ninu eko Iwe-mimo, ki o si k'ogo-ja ninu idanwo kan ti a npe ni Higher Division Clerical Examination.

Bawo ni iba tt dun to, bi o şe wipe Oyinbo pelu Enia Dudu ni a ndanwo po bayi, Oyinbo miran iba bole pirapira.

Iwa buruku kan ti Ijoba nhu nisisiyi ni aşa ki a ma fi ogede awon odomodekunrin wa si "Ijo Oyinbo" laibikita, nigba pupo, fun awon agbalagba aşiwaju won nibe: papa nigbati o şe wipe Ijoba papa na ni o lo pupo ninu awon agbalagba wonyi lati kekere titi nwon fi di arugbo, ti irun funfun nyo li ori won.

A mo wipe die ni iwe agbalagba miran fi ju ti Akowe alagbon lo, ati wipe agbalagba miran ko fe ilosiwaju omode rara, ati işubu re. Şugbon gbogbo agbalagba ko ni ko mo iwe, gbogbo won ko li o ni ika. Ika odomode miran tile buru ju ti Ibakasie lo.

Nigbakugba ti a ba ngbo irohin ilosiwaju omo de ni ibi işe Oba, nşe ni inu wa ndun lopolopo, o si je ohun ibanuje lati ri wipe, nisisiyi ti işe Oba san die, awon agbalagba ti o ti nba won jişe-jiya lati odunmodun yi wa ndi eni itanu; nitori kini? Ko nşe wipe nwon ko mo iwe, ko nşe wipe nwon ko mo işe, bikoşe wipe nitori irun funfun ta-ta-t-nde ori won. Bi a ti nfe ilosiwaju omode, beni a nfe ti agbalagba pelu; je-ki-nje l'o nmu ayo duna

Nipa oro ti awon Oyinbo ti a nso, inakuna owo ti Ijoba nna lori won, ko le je ki owo şeku pupo lati fi tun awon ilu ti o nmu owo yi wa şe, gege bi o ti to, ati bi o ti ye. Ogo ni Ijoba ndaba lati ya Munisipa ni egberun ona okole-rugba ponwun £220,000 fun kiko ile ati rira ile ni Yaba pelu ele (Interest,) bi eni wipe Ijoba oto, Munisipa oto, tabi, bi eni wipe atunşe ilu ko kan Ijoba to gege bi o ti kan Munisipa, beni arumoje ni gbogbo re

Nitoto, Munisipa ni lati duro gedegbe fun ara re, Ijoba si ni lati duro loto bakanna; şugbon Munisipa ile yi ha ri be? Bi otito oro ba de le, ki iro salo. Ko si Munisipa atata ni Ile yi, lasan ni ilu ni Aşoju meta nibe! Kareta lasan şa ni a fi nbo ara wa loju! Eka (Branch) ibi işe Oba, ni Şabu owo Omi, owo Erah, owo Tanwiji, owo Moto ti a npe ni Munisipa nisisiyi.

Nigbati Arun Ekute de si Oko Awo nijelo, idamu de si Ijoba, rogbodian wo ilu. Boya nigbana ni Ijoba to şeşe mo wipe adugbo na le mu ailera wa, ati wiye enia po nibe ju bi o ti ye lo. Lehinna, aisan yi de Idumeta, ati adugbo miran; a si dupe wipe, Baba np'etu si i nisisiyi.

Ni akoko aluba na, ni ero na so si Ijoba l'okan l'ojiji lati ra edegberin eka (acre) ile ni Yaba, lati ko egberun ile sibe, lati la ona ti o gboro dara-dara, lati fa omi sibe, ati Atupa Şango Electric Light).

Emi ni ti nyin nitoto,
ATARI AJANAKU.

The scientific Discovery of the nineteenth century for Female sufferers is

# WIRELESS FEMALE PILLS

***A sure remedy against all kinds of monthly disorders experienced by women, and an effective vitaliser against barreness. 4/6d per bottle of 72 Pills.***

# COOLING BLOOD PURIFIER

***A powerful blood purifier, cleansing the system of all impurities—approved by competent Medical Authorities. 7/6d***

# LIFE TONIC TABLET.

***A Renewer of Youth. 3/-***

# KADUNA BALM

***'The family Balm' applicable in 100 ways! 1/-.***

At present sold only at :—

# Iyin Oluwa Medicine Stores

*Head Office* :—88, Broad Street, Lagos,

6, Martins Street,

41, Alli Street, Faji Market,

22, Agarawu Street,

109, Griffith Street, Ebute-Metta

**Note our new Shop's address.**

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.* —NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

EỌMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nịẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as :— Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B :—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko bela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune !!!

---

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

## Indents House.

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

# TO LET.

## One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

——— : o : ———

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.